**Owe**

Adię iba l'oko, iba f'atitan se nkan. Imado iba je bi elede ti ba'le je. Eru to f'oba, enia ko ba ti ko ol...

# ELETI OFE

A-NJU-WON KO SE WI ... EJO

**Asoje**

Enia ma jeki t'enia sunwon, t'eni ma sunwon ko ni gbo. Apa omode ko le ka iti Ose, yio ma doyika.

VOL. XIII No 68. LAGOS. SATURDAY JANUARY 21, - JANUARY 27, 1961 KOBO MEJI (2D)

# OKU DI PUPO, ARIWO TA GEE! IYA ELEDIE KU OKIKI GB'ODE

EKO -- Iya agba kan ti nwon npe ni Iya Ęlędię, ti o wa ni Opopo Ępę, ni Ępetędo, ti o je ab'orisa, isę işegun ni a gbo wipe iya Olorisa na nse oku, awon ęgbę ati ogba pęlu awon aladugbo ati alabagbedun ni nwon wa ba awon ọmọ rę şe aisun oku iya na ni alę ojo Jimo moju Satide ojo kerin oşu yi. Aisun oku na dun, o pababmbari.

Nigbati nwon fe gbe oku iya Olorişa yi lo si itę-oku ni Ikoyi, a gbo pe awon ọmọ rę şe ape... lori awon Orişa ti iya na ko jọ sinu ilę, nwon si pinnu wipe ko si ęniti o mọ nipa awon Orişa ninu awon, nitorina nwon ko awon Orişa rę si ... posi pęlu oku iya Olorişa, nwon lọ sin oku ...

Nigbati nwon sin'ku tan ti ọpọlọpọ awon enia ati awon ọmọ oloku ko sinu Moto Munisipa ti o ngbe oku, ni moto d'orikọ ọna ilę. Bi moto na ti rin de ọkankan Opopo Lawrence si Igbosere, nibi ilę işę Moto awon S.C.O.A. beni moto na fo si meji lai kolu ohunkohun.

Awon enia inu re ... awamoto paapa ni o d... aşubu-lebu, ti nwon ngb'okiti lori arawon. Nwon ko awon enia ti ... farapa lo si ile iwosan, şugbon ope ni fun Olorun, ko si ęniti o ku ninu won.

## Olori Alufa Fise Sile

London - Olori Gbogbo-gbo awon Alufa ęsin igbagbọ (Arshbishop of Canterbury) Dokita Geoffrey Francis Fisher ti a ... ewe karun iwe irohin wa yi pe yio gba ... ni ipari oşu may, ni agbo wipe o ti ... Olaiyeluwa Oba obinrin ilu Oyinbo. Olori Alufa yi ni ipo rę ga julọ ni ile isin ilu Oyinbo, ... si di ęni ọdun mętin-le-l... dorin (74 years) ... oşu May, 1961.

Dokita Fisher ... Oluko agba ninu ilę w... Repton, nwon fi jęyę Bişopu ti Chester ni odun 1932. O joye Bişopu ti London ni ọdun 1939, nwon si gbe ga si oye Primate tabi Archbishop ni ọdun 1945. O gbeyawo, o si bi ọmọkunrin mefa.

Dokita Fisher yi ni ... di Olori Alufa kę'a to ... şe silę. Oba obinrin ti yan Archbishop Arthur Michael Ramsey ti ilu York lati rọpo Dr. Fisher.

## Nkan Itan Meji Sele

EKO - Larin wakati mę-ęnle-logun sirawon ni nkan itan konigbagbe me-ji ... lę, ọkan ninu Eko, nilę



... Washington ilę Amerika.

Ni ọjọ 19/1/61 ni Olọla nla Dr. Nnamdi Azikiwe P.C. Gomina Gbogbo-gbo ilę Nigeria di Oloye nla Oga awon ọmọ ogun ti ori ilę ati ti oju-omi, eyiti nwon npe ni "Field Marshal ati Admiral of the fleet" ti o ję oye ti o ga julọ ninu işe ologun. Nigbakugba ti asiko ati lo aşọ ... wony ba de ni Gomina ... yio ma lo won.

... isęlę konigbagbe ... ti Baba-ęgbę ilę Amerika, ti a le pe ni ọba ..., Dwight D Eisenhower, ti a mọ adape rę bi ..., jade kuro ninu "Ile ... fun" (White House) ni ọjọ 20/1/61 lęhin ọdun męjọ ti o fi şe ijọba nibę, ... fi aye silę fun John F. Kennedy, Baba ęgbę titun ti ... ilę Amerika.

K... nigbagbe ni isęlę mejeji yi ję.

# EJEKI OBINRIN DIBO

ILORIN -- Awon ęgbę Afęnifęre (Action Group) ti tun ... ti idibo obinrin dide ninu gbogbo idibo fun yiyan awon enia si igbimọ nilę Ariwa.

Ninu ... aşiwaju ... Talaka Parapọ dapọmọ ęgbę Afęnifere Alhaji Sule Maito ke si ijọba Ariwa wipe ki nwon tun da ọrọ won ro, ki nwọn yọnda ki awon obinrin le dibo ni ipinlę won.

Awon ęgbę Afęnifęre (A. G.) wipe ninu iwe ... ilę fun idibo ni Ariwa, awon obinrin poju ọkunrin lọ ni ilępo, ni ọpọlọpọ awon ilu ipinlę Ariwa.

# OLOTU IJOBA IWO-ORUN SE ALAYE OWO KOKO

IBADAN — Ninu ipade ti awon agbe se ni Gbongan nla (Western Hall) ilu Ibadan, ti Olotu ijoba Iwo-orun Oloye S. L. Akintola se alaye fun won lori owo Koko ti o dinku, gegebi o ti ri ni gbogbo oja agbaiye.

Oloye Akintola so fun won wipe gegebi oro ti awon gbo lati awon ilu Oke-okun laipe yi ko si wipe owo koko le g'oke tabi ki o yipada si rere niwon odun die si, bi igbimo ijoba ti o nta Koko ba nsan owo re gegebi ti isisiyi ti o je ogojo ponun (£160) fun tonwun kan yio padanu bi adota-le-l'odunrun oke ponun (£750,000) si irinwo oke ponun ni asiko oja Koko kansoso.

Osi tun ranawon agbe leti ise ribiribi ni ara lowo ti igbimo Ata Koko ti se lori fifi kun owo Koko fun awon agbe ipinle Iwo-orun ti nwon fi nsba ogojo ponun (£160) fun tonwun kan ni asiko oja Koko, nigbati nwon san ponun mejile-ladofa (£112) fun awon elegbe won nile Ghana lati odun de odun 1954 — 1955.

Lehinti Olotu ijoba Iwo-orun se gbogbo alaye wonyi tan ni o so fun awon agbe wipe ki nwon ro bi nwon yio ti se ran ijoba lowo ninu ohun ti o de'le yi.

Oloye S. L. Akintola tun se pahambari alaye lori oro Koko nilu Ogbomoso gege bi igbimo Ataja Koko ti ipinle Iwo-orun ti san owo giga fun agbe lati nkan bi odun marun sehin.

| | Nig. | Gha. |
|---|---|---|
| Ni odun | | |
| 1955-56 | £200 | £149 6/8 |
| 1956-57 | 150 | 149 6/8 |
| 1957-58 | 150 | 134 6/- |
| 1958-59 | 150 | 134 8/- |
| 1959-60 | 160 | 112 0 0 |
| 1960-61 | 160 | 112 0 0 |

Oloye Akintola so wipe igbimo Iwo-orun ko nna makuna gege bi egbe N.C. N.C. ti nse, ni o je ki nwon le san owo giga fun awon agbe ipinle Iwo-orun lori Koko.



AWON AGBE SE IPADE ASIRI

Nigbati awon agbe pari ipade tiwon ti nwon se ni Baba egbe ajumose ... ipinle Iwo-orun ile Nigeria, Oloye Akinpelu Obisesan fi iwe ipinnu ti awon agbe fe le Olotu ijoba lowo.

Pataki ipinnu ti awon agbe ... ajumosepo ati awon egbe agbe ... ti ijoba ti nse fun awon ... adagbasoke odun marun ... o je ti ire ati anfani awon agbe, awon si ... gidigidi fun ijoba.

Awon parapo, awon si f'ohun sokan wipe ona-kona ti ijoba ba ro wipe yio dara, ti ijoba ba si mu se, ni awon fi ara mo.

Oloye Akintola dupe lowo awon agbe fun ero rere won, o si mu won mo daju wipe ijoba ko ni kere nidi atunse owo Koko fun awon agbe.

Iyoku ni iregbe, gbogbo awon agbe oni Koko ti o wa ni ipinle Iwo-orun ti f'aramo edinku owo Koko.

# OLOPA YO ENITO BE SINU KANGA

SOMOLU - Opelope awon olopa ati Panapana ti nwon pe lati Eko wa si Somolu ni o se igbala okunrin kan ti o ro ara re pin ti o si fe pa ara re nitoripe ko ri ise se, o si ni gbese lorun.

O to nkan bi ogbon iseju ti awon olopa ati Panapana fi se wahala ki nwon to le yo David Emerue ti o ko sinu kanga ni ireti ati pa ara re, ko fe mu okun ti nwon ju si 'ani lati fa gun oke. Aiko tin ju ese mewa lo niko je ki o ku sinu kanga na, o wa ni ile iwosan Ikeja nisisiyi fun itoju.

Nwon so wipe David wa lati ilu Kano niwon bi osu mokanle-logun s'ehin lati wa ise se nilu Eko, sugbon ko bo si. Ile odo baba re nipa ti Olorun ni ongbe, Ogbeni Alphonsus Okpara, akun - oda ti Opopo Apata, ni Somolu, ninu ile na ni David ti fe pa ara re

Ohun ti o mu gb'ero buburu yi ni bibawi ti baba re nipati Olorun bawi fun gbese ti o nje nitoripe awon owo ti o nya lowo awon enia fere to ogun ponun.

Sugbon Ogbeni Okpara so wipe on ko ba ja, ni otito ni on so fun pe ko si on ti o mu lati ma je gbese niwon igbati awon nkan ti o nlo ko ti won.

Laipe na ni awon omode ti o wa ninu ogba lehinkule kigbe pe David be sinu kanga. Awon olopa da Alphonsus, baba David nipati Olorun duro si Kotu fun odidi ... ti awon fi mbere oro lenu re ki nwon to ju sile.

# ILU IJEBU-ODE KO AJA

IJEBU-ODE — Igbimo ibile ilu Ijebu-Ode ti pase wipe ilu Ijebu-Ode ti pase wipe ilu Ijebu-Ode ati agbegbe re, ni iwon ibuso mefa yika ilu ti gbajukan fun arun digbolugi.

Nitorina, enikeni ko gbodo mu aja jade tabi ki o mu aja wolu ni agbegbe Ijebu - Ode. Gbogbo aja ti won ba ri di piparun.

# Itan Aja Ati Awọn Eranko

(Lati ọwọ ọmọ " Olumọ ")

NI igba lailai Aja ati awọn ẹranko jijọ nṣe ọrẹ pọ, nigbati o pẹ awọn ẹranko ni ki gbogbo wọn jijọ pa iya wọn jẹ gbogbo wọn si gba bẹ, olukuluku npa iya tirẹ nwọn si njijọ jẹ, Ajapa na si pa tirẹ na pẹlu.

Ṣugbọn nigbati o kan Aja, aja ko pa tire, o mu lọ si orun, o lo fi pamọ ti ebi ba npa yio lọ si ọdọ re lati lọ jẹun, nigbati o pẹ ebi npa awọn ẹranko yoku aja si nyo o si dan pelu o si nya awọn ẹgbẹ re yoku lenu wipe ibo ni aja ti nri onje jẹ ti o si ndan bayi ? Ajapa ni on yio wadi lọwọ re.

Ajapa si lọ so ba Aja fun iwadi na, obi Aja lere wipe, Aja e fi ona han wa. Aja ni fi ona han yin bawo ? Ajapa ni ki o fi ona ibiti o ti nri onje han on nitoripe ebi npa on iwọ si nyo, o si ndan, o si nyọkun.

Ajapa si bẹ Aja lọpọlọpọ lati fi ọna han, Aja wa sọ fun wipe, bi o ba fẹ ki nfi ona han ọ, ki o ṣe ẹnu rẹ mọran, nitoripe tu-aṣiri-tu-aṣiri ẹda ni Ọlọrun da iwọ Ajapa, Ajapa bura o fi Ọlọrun ṣe ẹri wipe on ko ni sọ fun ẹnikan rara. Aja ni ti o ba di ọla ni dede agogo meji irọlẹ ki o wa lati lọ jẹun lọdọ iya on ni ode-ọrun.

Nigbati o di ọjọ keji, Ajapa lọ ba aja ni ile won lati lo, ṣugbọn ẹru mba Aja wipe ki ajapa ma ba nkan jẹ fun on, Aja ni Ajapa, jọwọ ibiti mo ma mu ẹ lọ yi ki iṣe ibi ṣere-ṣere rara ti o ba ṣe ẹnu rẹ furu iwọ yio ma jẹun ni ọdọ iya mi titi lailai.

Bi nwọn de ti ṣe de ọdọ iya aja.

E o ma gbọ yoku ni ọsẹ ti o mbọ.

---

# Isinku Iyawo Bisopu Kamama

EKO — Iyafin Aduke Howells ti o s'alaisi ni Ifọ ni ọjọ Alaruba (Wednesday) lẹhinti o ba awọn inade obinrin Ijọ Anglican sọrọ tan, ni a ṣe isinku re ni ọjọ Jimọ (Friday) ti iṣe ọjọ kẹtala oṣu January, 1961.

Enia po bi omi ti o wa sibi isinku na, Eni - ọwọ Bisopu S. O. Odutọla ni o ṣe isin ikẹhin fun oku na ninu ile isin nla, Christ Church l'Ehingbẹti l'Eko.

Alufa Ashley-Dejọ ni o ṣe iwasu le ori oku na, o si ṣe apọn'e ologbe na wipe eniti o wulo larin ebi, ninu ile isin ati paapa fun gbogbo enia ni iṣe.

Nigbati nwọn nrẹ eṣikusile korofo Iyafin Howells tẹ sinu ilẹ ile re ni Ikoyi, ni Ẹni-ọwọ Bisopu bu sẹkun.

Ki Ọlọrun foriun kẹ ologbe na, ki O si gbe si afẹfẹ rere.

---

# Eni Adojo Odun Fese Rin Adota Ibuso

SRINAGAR — Laipẹ yi baba agba arugbo kan fi ẹsẹ rin lati ilu rẹ ti o jẹ bi iwọn adajọ ibuso lati wa pade Olotu ijọba ilu Kaṣimia Kashmir baba na pe ara rẹ ni "Ay'pada'rua"

O sọ fun Olotu Ijọba Bakashi Ghulam Mohammed wipe abule on ti o wa ni ẹgbẹ Lolab Valley afẹ ilewe, Ọpopọ ọna ati awọn nkan miran ti o dara fun ilu.

Baba agba na sọ wipe on ko ni bere fun ile iwosan nitoripe awọn obi on ti sọ wipe ko dara ki iru ile bẹ wa nitosi.

Lati nkan bi ọgọrun odun s'ẹhin, eyi ni akọkọ ti on yio wa bẹ ilu wo, ko si rorun fun on lati ma rin kiri ilu Srinagar gẹgẹbi awọn ẹda titun ti o wa ninu ilu na ti nwo on tifura-tifura yi, awọn nkan igba laila ti yipada.

Baba agba na lọ sọdọ Akọwe ẹgbẹ National Conference ti o wa ni Ajaṣe ilu Srinagar, ẹniti o pe wipe ki o wa wọ ẹgbẹ wọn. Nigbati nwọn bi lere wipe ba wo ni imisi rẹ ti ri bi o ti dagba to yi ? O fesi pe awọn onia nṣe ilara ẹmi gigun ti Ọlọrun fi ta on lọrẹ ni. Oa fẹ dagba to gẹgẹbi iwọ na ba ti fẹ to.

---

# Ero Itewe Ti Gesi Se Ise Daradara



Ọmọ ile Nigeria ti o lọ'sibi ifihan'ehun elo ise ti nwọn ṣe nilu London laipe yi ni Ọgbeni O. A. Kuku lati ilu Eko, ni o nwo ero itẹwe ti Oyinbo Gẹsi ṣe, iru eyiti ijọba ile Nigeria ra mẹdogun fi tẹ iwe idibo ti awọn adibo ijọba apapọ ilẹ Nigeria.

Bi ero na ti nra tẹ iwe to, gbogbo iṣẹ na ni o ti pari tan ni nkan bi ọsẹ mẹta ki asiko to to.

# ELETI--OFE

ANJUWON KO ŞE WI L'EJO

EDITORIAL OFFICE & WORKS CABLES & TELEGRAMS

28, Kosoko Street, Lagos. "ELETI OFE, LAGOS

P. O. Box 467 Phone 23370

VOL XIII. NO. 681. SATURDAY JAN. 21, JAN 27, 1961


# IGBONRAN SAN JU EBO LO

Ifetisile san ju ora agutan lọ. Bẹni ọrọ na wi ninu iwe Mimọ Bibeli. Ni ọsẹ ti o kọja, ninu iwe irohin wa Eleti-Ọfẹ yi ni a ti şe ikede ati imọran fun awọn enia wa nilu Eko ati ni Oke Ebute-Mẹtta wipe ki olukuluku enia maşe jafara lati lọ bupa (Vaccinate) fun idabobo nitori ajakolẹ arun ilẹgbona, gẹgẹbi ikede ti ijọba şe.

Awọn Yoruba ni o ma npa l'owe wipe: "Bi Egungun ẹni ba njo're ori yio ma ya atọkun rẹ". A ro si ẹtọ ati ẹyẹ lati yin awọn enia wa, l'ọkunrin ati l'obinrin, l'ọmọde ati agba fun akikanju wọn ti nwọn fi nlọ bu apa na. Eyi jẹ iwa ti o dun mọ wa nitoripe bi enia ba nşọ ara rẹ, Oluwa yio ma şọ ẹnibẹ.

Awọn ti ijọba sọ wipe nwọn ti bu apa lati ọjọ kẹsan oşu January ti ikede ti jade titi di ọjọ Satide tokọja fẹrẹ to ọkẹ meje enia nilu Eko ati Ebute-Mẹta.

A gbọ wipe titi di ipari oşu yi ni aye yio fi wa fun apa bibu na, nitoribẹ, ki ẹniti ko baiti lọ bu apa tirẹ maşe jafara, afara nija ẹkun.

## Nwon Yinbon Pa Omo Odun Mefa

ILE-IFẸ - Ọkunrin kan ati ọmọ rẹ ti o to ọmọ ọdun mẹfa nlọ si oko wọn ni Ile-Ifẹ, nigbati nwọn de arin ọna larin igbo ni ẹnikan yinbọn lati inu igbo ti o wa pa ọmọ na ni apafọn.

Baba ọmọ na sọ wipe oko ni awọn nlọ lati lọ wa gbaguda ki nwọn to yinbọn pa Edumc lseu, ọmọ on ọkunrin, ọmọ ọdun mẹfa.


M.B.T.

(MAGIC BLOOD TONIC)



[illegible]

ARADAN STORES P.O.Box 2

EBUTE-METTA


# OLE JA NILE ADURA

IBADAN – Awọn ọmọ ẹgbẹ Serafu ati Kerubu ti o wa ni Oke-Ado nilu Ibadan, jade lọ şe isin ode gbangba ninu ọsẹ tokọja ki nwọn to pada si ile isin wọn, ole ti ji ẹru wọn ko lọ.

Awọn ẹru ti ole ji kona ni awọn aşọ adura, aşọ wiwọ miran ati awọn ohun ọşọ ile ti o le ni ọgọrun pọnun ni awọn ole na ji ko lọ.

Iya Aladura ti o njẹ Comfort George ni o padanu pupọ ju. O sọ fun awọn ọlọpa wipe ẹru ti on nik'an ti wọn ji ko le ni pọnun marun-le-ladọrin ati şile mẹwa. Owo şile rẹ ti nwọn ji pelu jẹ pọnun kan abọ.

Irohin miran ti a tun gbọ niti Ile onjẹ ti nwọn npe Green Springs Hotel, nilu Ibadan, ni nwọn fi mọto kan silẹ niwaju ile na pẹlu apo ifadani kan pẹlu nkan bi ẹdẹgbẹta pọnun ninu rẹ ni nwọn ji apo na lọ ninu mọto na.

# AWON ENIA PATAKI META J'OYE NILU ILORA

ILỌRA - Ni ọgbọnjọ oşu kejila ọdun tokọja 30/12/60. ni nwọn fi awọn gbajumọ enia mẹta j'oye nilu Ilọra. Nwọn fi Olugbimọ ile igbimọ nia (Senator) Ọlọla S. Eyitayọ jẹ oye Ẹkẹrin ilu Ilọra, Ọgbẹni J.A. Mosebọlatan jẹ oye Bariyun ilu Ilọra ati Ọgbẹni E. Ogunrombi jẹ oye Ọdọfin. Ẹniti o şe eto ifinijoye na ni Oloye D.A. Ọparinde, ti o jẹ ọkan ninu awọn igbimọ Lọbalọba.

Lẹhinna ni Lemọmu agba ilu Ilọra şe Adura fun ilu ati awọn ti o j'oye, Ọgbẹni D.K. Sangonte na şe adura pẹlu. Ọlọla S.O. Kọlade ni o şọrọ işiri diẹ nibẹ lọjọ na. Lẹhin eyi ni nwọn şe ipanu fun awọn ti o wa sibi ifinijoye na ninu ile Balẹ ilu Ilọra.

Awọn gbajumọ Ọlọla ati awọn Ijoye ti o fi ọla wọn wa bukun ifinijoye na ni : Awọn ọmọ Alafin ati ọpọ enia lati Ọyọ, Awẹ, Balẹ Fiditi ati awọn enia rẹ, Balẹ Akinmọrin, Oko Agbẹ Oluwa-tẹdo, Oko Agbẹ Aiyelagbe ati awọn enia ilu Ibadan. Ọgbẹni T.O. Ọ'anipẹkun lati Akurẹ, Ile-Ifẹ, Ijẹbu-Ode.

Enia pọ ti a kole daruko wọn tan.


# OKU'JA WOLU

NIGBATI ỌJA KO BA TA, TI ẸNITI O NRA ỌJA KO TA EYITI O RA, BAWO NI YIO TI ŞE LE RA OMIRAN. EYI NI OGUN TI ONIŞOWO LE ŞE TI ỌJA RẸ YIO FI MATA BI IŞU AKARA GBIGBONA.

E polowo Oja Yin

Sinu Iwe Irohin

ELETI - OFE

## Arun Digbolugi Wolu Ijebu-Ode

IJẸBU-ODE — Ninu oṣu to kọja ni obinrin kan ati ọmọ rẹ obinrin ni a gbọ wipe arun digbolugi kolu nilu Ijẹbu-ode, eyi ni awọn ṣe kede arun na, ti nwọn si ṣe npa awọn aja nitori arun na.

Sugbọn enia meri ni a tun gbọ wipe arun digbolugi pa nilu Ago-Iwoye nitosi Ijẹbu-Ode. Lehinti ijọba ti ṣe ikede wipe arun digbolugi wọ ilu Ijẹbu-ode niti Agọ-Iwoye yi tun ṣẹlẹ.

Latigbana, akoiti tun gbọ pe arun na kolu enia awọn enia ti o si ti kolu nlọ fun itọju daradara ni ile iwosan (Hospital).

## AWON EJO KOTEMILORUN

EKO — Awọn ẹjọ kotẹmilọrun ti nwọn yio ṣe ni ọjọ kẹtale-logun oṣu January 1961 ni Kotu nla nilu Eko niwonyi:

Ẹlẹjọ ni Mobil oil Nigeria Ltd. pe Ọlọla J. M. Johnson. Ẹlẹjọ ni Abigail Folashade pe Alhaji A. A. O. Durosola Ẹlẹjọ ni Mobil oil Nigeria Ltd pe Afolabi Lagunrodunmi.

Eyi nitu ọjọ ketadi-logbon oṣu March, 1961. Ẹlejo ni Continental Press Co. Nigeria Limited. Alade Lawal, Dona Ekanem, pe Reginald Banham Allen ati Derby Allen.

Eyi nitu ojọ ketadi-logun oṣu April, 1961. Elẹjọ ni West African Pilot, P. C. Agu pe Ọlọla Rotimi Williams, Ọlọla S. L. Akintọla ati Ọlọla Ọbafẹmi Awolọwọ.

## Nwon Yinbon Pa Ni Tabi O Pa Ara Re

AKURẸ — Ọpọlọpọ ọuẹ ni awọn ọlọpa ti ṣe iwadi lẹnu wọn nipa iku ti o pa ọkunrin Isebo, ọdẹ kan ti nwọn npe ni James Ipo ti nwọn ri oju ọgbẹ ibọn ni igbaiya oku rẹ ni ọjọ kọkandi-logbon oṣu December 1960.

James, ọmọ ọdun mẹriadi-logoji, ti o bi ọmọ meji ni o lọ ṣe ọdẹ igbo ni abule Atosin nitosi Akurẹ nigbati iṣẹlẹ buruku yi ṣẹlẹ.

## Olotu Ijoba Ile Nigeria Nilu Oyinbo



Olotu Ijoba Ilu Oyinbo, Ogbeni Harold Macmillan ni a nwo ninu aworan yi, ti o nbọwọ pẹlu Olotu Ijoba ilẹ Nigeria, Alhaji Sir Abubakar Tafawa Balewa nigbati o njade ninu ile rẹ lẹhin onjẹ ọsan ti Olotu Ijọba Nigeria lo ba jẹ.

Eyi ni asiko ti Olotu Ijọba Nigeria lọ bẹ ilu nla London ọ lẹhinti o kuro ni ipade ẹgbẹ Majẹobaji agbaiye ti nwọn lọ ṣe nilu New York.

## Olori Alufa Esin Igbagbo Yio Gba Isinmi Afehinti

London – Irohin ta siwa leti lẹnrẹ lati ilu Oyinbo wipe Olori Gbogbogbo Alufa esin igbagbọ Dokita Geoffrey Fisher, (Archbishop of Canterbury) yio gba isinmi afẹhinti ni ọjọ kọkanle-logbọn oṣu May, ọdun yi.

Iro ti a tun gbọ balaina leti ile iṣẹ Olotu Ijoba ilu Oyinbo Gesi nipe Ayaba Elizabeth Keji Ọba obinrin ilu Oyinbo yio fi oye nla (Peerage) da Olori Alufa, Dokita Fisher lọla nigbati isinmi rẹ ba bẹrẹ.

E MA KA IWE IROHIN ELETI-OFE L'OSOSE

## Odaran So Fun Adajo Wipe Ole Jija Ni ISe Wa

MAKURDI - Audu Gimeta, ọmọ ọdun mẹtalc-lọgbọn ni nwọn ju sẹwọn ọdun mẹta pẹlu iṣẹ aṣegan fun ẹsun wipe nwọn lọ ji eru ko ni ṣobu Ọgbẹni Duru, Oniṣowo ilu Makurdi. Ẹnikeji rẹ ti o nje Baba Yali ni nwọn ju sẹwọn bakanna.

Awọn ọlọpa ni apelẹwọn ni awọn ọdaran mejeji. Adajọ bere wipe nwọn jẹbi tabi nwọn ko jẹbi? Awọn ọdaran na bu serin, nwọn si so fun adajo wipe, o kan nlo akoko rẹ ṣofo lasan ni bi bi ti o mbi wa lere bia jẹbi tabi a ko jẹbi nigbati o ti mọ wipe ole jija ni iṣẹ wa.

Lẹhinti adajọ ṣe idajọ ẹwọn fun wọn tan ni ọdaran kini yi pada lo wo Ọgbẹni Duru, o sọ fun wipe o ṣ'orire ti a ko pa ọ l'oru ọjọ ti a fọ Ṣọbu rẹ.

## EJO AROTUNRO NI KOTU KADUNA

KADUNA — Ọgbẹni Josiah Sunday Ọlawọyin ti iṣe ọmọ ẹgbe Afenifere (A.G.) nilu Ọffa, ti o si jẹ ọkan ninu awọn ọlugbimọ nile igbimọ Aṣofin ti Ariwa nile Oke-Ọya, ti nwọn ju s'ẹwọn oṣu mẹfa nilu Ilọrin ni o ti je iwe si Kotu wipe ki nwọn yọ "Grand Kadi" kuro ninu awọn adajọ ti yio gbọ ọrọ ẹbẹ ẹjọ arotunro rẹ ni Kotu.

Agb'ẹjọro rẹ, Oloye F.R.A. Williams Q.C. yio tun fi siwaju Kotu giga ti Kaduna wipe ki nwọn da Ọlawọnyin ati awọn enia mẹfa ti nwọn jijọ ju s'ẹwọn silẹ titi di igba ti nwọn yio fi pari ẹjọ wọn ni Kotu Arotunra.

Ninu oṣu November ọdun to kọja ni nwọn ju wọn s'ẹwọn ni Kotu Onipo kẹta, ni Ilọrin lori ẹsun wipe nwọn fa ijọngbọn nilu Ọffa.

## Nwon Fi Akowe Onisowo Sun Esun Ole

EKO — Raji Akeredolu ti iṣe akọwe ni Ṣọbu awọn Oyinbo Oniṣowo (P. Z.) ni nwọn fi sun ẹsun ole niwaju adajọ ni Kotu giga tilu Eko, wipe o ji eru bi oni £1,700 ti awọn oniṣẹ rẹ.

Ẹniti o ko jẹri mu iwe kan wa siwaju adajọ ti o wipe Akeredolu ko wipe otitọ ni on ji aṣọ funfun igan 1,525 ko, ti iṣiro owo rẹ jẹ £1769 5/- o si wipe on ni o sọ fun Raji Akeredolu wipe ki o jẹwọ otitọ ki a ma ṣe iyọnu iwadi nitoripe nwọn ko ni sai ri idi rẹ, Akeredolu ni nwọn so pe o daruko enia meji pẹlu ara rẹ ti nwọn jijọ pin eru na.

Ṣughọn Loya rẹ Ọgbẹni A. K. I. Makanju so siwaju adajọ wipe ki nwọn maṣe gba jẹjẹ na ṣi ohun ti a le fi rojọ, o si ka ofin le lori. Adajọ fi aṣẹ rẹ dirojọ ko kan de dologun oṣu January 1961, o si gba idụro fun Akeredolu lori £800.

## OMOBA ALXANDRA SI ERO ISORO



ENITI a nwo ninu aworan yi ni Ọmọba ilu Oyinbo, Alexandra ti Kent, nibiti o ti nsi ero isoro titun ti nwọn ṣeṣe se ninu ile iṣẹ Ifiweranse. Nibe ni i o ti nfi ẹro na ba Sir. Adesoji Aderemi, Gomina ipinlẹ Iwo-orun soro ni'lu 'ba'an iwon nkan bi adorun buso si ilu Eko. Ọlọla Olu Akinfosilẹ, Alaṣẹ ile iṣẹ Ifiweranṣẹ ni o joko si apa otun yi.

Ọmọba na ni o wa se olu fun Alayeluwa Ọba obinrin Elizabeth Keji, ni gba ariya ominira ilẹ Nigeria nilu Eko.

## Ejo Agenilowo De Kotu

IBADAN — Ni ọjọ keji ọdun Keresimesi ti nwọn npe ni Boxing Day ni rogbodiyan ija kan bẹ silẹ larin Yoruba ati awọn Ibobo nilu Ikire nitosi Ibadan.

Nigbati Jacob Onunaduen jẹri ni Kotu ni o tọka si Samuel Ozuem ti nwọn fi sun ẹsun wipe o ṣe ipalara fun ẹniti o ba ja, wipe eniti o ge on lọwọ na ni yi.

Ọrọ yi ṣẹlẹ nigbati ija kan bẹ silẹ, o sọ wipe Samuel le on jinna ki ọwọ rẹ to tẹ on ti o si fi ada ge apa osi on silẹ, on si mu apa ti oge na sare lọ si ile ki nwọn to gbe on lọ si ile iwosan ti Ile-Ifẹ fun itọju.

Nwọn fi gbigbọ ẹjọ na si ọjọ kẹdọgbọn oṣu yi.

## IJOBA FARANSE FE POHUNDA

Irohin kan wa wipe ijọba Faranse npete-pero lati ko awọn ohun elo ti nwọn fi nwọn fi adan ẹtu Oloro wo kuro ni Reggan ilẹ okun yanrin Sahara lọ si ilẹ Antarctica, Kergulen.

Gbogbo ilẹ Kergu'en kekere na ni nwọn npe n "Ilẹ ti enia kọ silẹ" ri, ni o wa ni apa Iwọ-orun okun India iwọn nkan bi ẹdẹgbẹta-le-lẹgbẹrun ibusọ si Antarctic.

Ijọba Faranse ni o ti ni ibẹ lati nkan bi ọdun 1772, awọn si ti fi awọn ọjọgbọn oluwadi sibẹ lati ọdun 1942.

Ijọba Faranse nfẹ ṣe eyi nitori atako ti awọn ilẹ enia dudu npe ni. Eyi fihan' wipe iyirapada wa si-lu Faranse lpau ọjọ mẹta yi ṣẹ nje iṣẹ.

## Moto Kolu Enia Dereba Salo

OWERRI — Awọn ọlọpa nwa awamọto (Driver) ti o kọlu enia kan ti o gun kẹkẹ-ologere tabi basikulu lọna Owerri si Okigwi ti o salọ ni ọjọ Satide tokọja.

Ẹniti o gun basikulu na ni orukọ rẹ njẹ James Duru, o si farapa pupọ, nwọn ti gbe lọ si'e iwosan (Hospital) nilu Owerri

## Enito Ba Won Ja W'ewon

IBADAN - Ọkunrin gara-bari kan ti wọn npe ni Tanko Katsina ni adajọ ju s'ẹwọn oṣu mẹfa nilu Ibadan fun ẹsun wipe o lu enia nigbati o mba wọn ja. o dupẹ lọwọ adajọ e si wipe "Nagode Allah"

Tanko yi ni wọn ti fi sun esun meji fun ole afọle wipe o lọ ṣọbu lati jale, o si lu enia meji ni ad jọ da silẹ nigbati ke si ẹri fun won.

### ẸNITO GUN IGI LỌ KA ESO JALULẸ KU

OWERRI - Ọkunrin egbẹ ara ilu Owerri kan, Ndukaaba Nnoka, ni o gun ori igi giga kan lọ lati ka eso igi na fun iyawo rẹ, lojiji ni ọwọ rẹ yọ bọrọ lara igi na o si ja lulẹ, tẹ ni o ṣe ku bam-bam.

O fi iyaw rẹ ati ọmọ meta sile aiye Lọwọ iku ojiji Oluwa rere gba wa.

## Ejo Ti Egbe Alakuko Pe Ijoba Iwo-orun

IBADAN — Nwọn fi ẹnu ba riro ẹjọ ti egbẹ Alakukọ N. C.N.C. ti o jẹ alaṣẹ Igbimọ Ilesha ti ijọba tuka pe Ijọba Iwọ-orun ni Kotu, nwọn si yẹ riro ẹjọ na si ọjọ kẹtala oṣu February, 1961.



Oloye Rotimi Williams ni o wa pelu agbẹjọro ijọba, Ọgbẹni B. Olowofoyeku ni o wa fun awọn ti o pẹjọ.

## AFIHAN GBOGBO-GBO NILU OYINBO



Ọgbẹni I. C. Ugwa lati Enugu ni ipinlẹ Ila-orun, Nigeria, ati Aṣoju ilẹ Canada nilu Oyinbo, Ọlọla nla George, A. Drew. Q. C. ni a nwo ninu aworan yi nigbati nwọn gba duro niwaju ile iṣẹ BEWAC, nibi Afihan gbogbo-gbo ti nwọn ṣe nilu Birmingbon laipẹ yi.

## Shell Recognises Trade Union

The Shell Company of Nigeria Limited recently accorded recognition to the UNION OF SHELL OPERATIVES at a ceremony held at the Shell House, Marina, Lagos.

An agreement of procedures of negotiation was signed by Mr. W.I. Stewart the General Manager of the Company and Mr. J.A.O. Ubiku, President of the Union.

The agreement clearly states what subjects shall be decided by collective bargaining as distinct from those by joint consultation and also sets out the machinery and methods of negotiation between the union and the Company.

Mr. M.C.O. Falade, of the Company's Personnel Department offered, on behalf of the Company, co-operation with the Union and stated that he was sure that the Union would use reason in their demands and negotiations.

The Union President, Mr. J.A.O. Ubiku, in his address thanked the Company for the recognition accorded the Union. He went on to say "This expressed act of cordiality shows that in Nigeria where all the freedoms are guaranteed Shell considers that freedom of association is and important one and as such should be allowed to flourish".

The President promised faithfully to serve the Union and to assist the industry in increasing productivity.

The Assistant Industrial Relations Commissioner, Mr. Abiodun, spoke on behalf of the Ministry of Labour. He expressed his thanks for being invited to the recognition ceremony and said that the strength of any Union lies in its organisation. As such the Union should make every effort to establish a strong and effective organisation as soon as possible.

## Ijoba Ila-orun Fun Olopa Lagbara

ENUGU — Ofin titun kan ti nwọn ṣẹṣẹ ṣe ni ipinlẹ Ila-orun ni ijọba ti fun awọn ọlọpa l'agbara lati ma gba iwe aṣẹ lọ-rẹba mọto, awọn awamọto ti o ba ṣe ti ọlọpa ba ri wipe nwọn ko ni le tele ri wọn.

Ofin na jẹ atunṣe sinu Ofin oju ọna ti o ti wa nilẹ ni ipinlẹ na, ohun ti o si fa Ofin na wa ni wipe ẹsẹ ojuọna npọsi, awọn awamọto si npurọ fi orukọ ibugbe wọn silẹ ... ọlọpa ba mu wọn ... oju-ọna.

## ENITI NWỌN ... NI ... ARA RẸ

... Ọkunrin kan ni o ... ni Kotu ... pa ara ... fẹ ki nwọn ...

... Yakubu Ningi ... odo lati ori Kotu Carter, l'Eko. Awọn ... ti o wa nibẹ ni o yọ ti ko ... u.

Adajọ bere pe kiloṣe ti o fẹ pa ara rẹ ... Ningi sọ wipe Ọga on Yẹkini Busari ni o wi-pe on ji kọkọrọ rẹ. Adajọ so agbeje mọ nidi fun oju mejila.

## OGBOJU OLE DUPẸ FUN ADAJỌ

MAKURDI - Ọkunrin Ogboju ole kan Ọnoja Enabo, ti nwọn npe ada-pe rẹ ni "M ati B" ti awọn ọlọpa pe ni apelẹwọn fun adajọ ni nwọn ju s'ẹwọn oṣu mejila fun ẹsun wipe o ji agogo ... run ọwọ oni ponun mẹta ti ṣile medogun (£3. 15s) ti Ọgbẹni Sunday Ogale.

M ati B yi ni ẹniti nwọn ṣẹṣẹ da silẹ ni ọgba ẹwọn, ni ọjọ kanna ni o tun lọ ji agogo Sunday ni ṣọbu ẹlẹmu, ti o si ta fun Sule ni ṣile mejila.

NEW



FIAT 600

with 767 c.c. ENGINE

Full four seater Improved ventilation with new window deflectors and fully winding glass. Collapsible rear seat for more luggage room and optional front reclining seats

Livelier Pick up, speed of over 70 m.p.h and traditional FIAT economy all round. New electro magnet starter and well proven full independent suspension on all four wheels.



Price:

ONLY £465

(including new duty)

... cheaper on Home Delivery.

£298 (Ex Turin)

LEVENTIS MOTORS

Lagos - Ibadan - Kano - Jos

Port-Harcourt - Aba

Printed & Published by The Union Printing and Publishing Company, 28, Kosoko Street P. O. Box 457 Lagos ...